Akiyesi

A nfẹ Ẹniti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imọlẹ, Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilu miran. Ẹ kowe si odọ Ọgbẹni: R. O. Adedeji Esq. Ni P. O. Box 12 Ilọrin

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE-DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma polowo oja yin sinu Irohin Imole

VOL. III No. 143 MONDAY MARCH 28 — APRIL 3 1960 KOBO KAN (1d)

# Awon Obirin oja Ereko ko jale lati fi oja Ereko sile

AWỌN OLORI OBIRIN ỌJA SỌ NI ỌJỌ JIMỌH PE AWỌN OBIRIN ỌJA EREKO, KO NI FI ỌJA WỌN ATIJỌ ṢILE FUN AWỌN ẸLOMIRAN LATI TAJA. NINU IWE KAN TI WỌN KỌ SỌWỌ SI ALHAJI MUHAMMADU RIBADU, ALAṢE ETO ILU EKO, AWỌN OBIRIN ỌJA YI ṢE ITỌKASI ỌNA TI IGBIMỌ ILU EKO FI FẸ MA PIN IṢỌ, WỌN WA FI GBE TA WIPE "A TI GBỌ WIPE AWỌN ENIA KAN NṢE BIRIBIRI NIPA ỌRỌ ỌJA, ATIPE NIṢE NI AWỌN ENIA YI BAKANNA NFI IPA GBA PỌUN MEJI SILE MEJI ATI PỌUN KAN SILE KAN LỌWỌ AWỌN OBIRIN NITORI KI WỌN BA LE FUN WỌN NI ISỌ, LẸHINNA NI AWỌN OBIRIN YI ṢẸṢẸ TUN WA NṢE ATUNTA IṢỌ NI PỌUN MARUN.

Iwe yi wa se ikilọ: "Awa olori Obirin ọja fẹ fi ye Alaṣẹ Ijọba pe, a ti wa lati san owo-ko-wo ti Ijọba ba fẹ ki a san lati ri pe iṣọ wa bọ si ọwọ wa, nitoripe ninu awọn iṣọ wọnyi ni a ti ntaja lati bi ọdun gbọ ṣugbọn afẹ ki alaṣẹ Ijọba mọ pe ni ayekaye. awa koni fi isọ wa wọnyi silẹ fun awọn ẹlomiran lati gba.

Awọn Obiurin yi wa ran alaṣẹ Ijọba leti wipe Igbimọ Eko ti ṣe ipinnu tẹlẹ ri wipe ti awọn ba ma tun iṣọ pin awọn ti o ti kọkọ wa ninu wọn tẹlẹ ni yio kọkọ ri isọ gba.

Wọn wa fi to eti alaṣẹ ijọba awọn ohun kan ti awọn kan ni ki awọn ṣe ki awọn to le ri isọ awọn gba pada. Wọn ni niṣe ni wọn sọfun awọn pe ki awọn to le gba iwe aṣẹ isọ awọn gbọdọ ra iwe ẹgbẹ alakukọ atipe awọn gbọdọ di ọmọ ẹgbẹ, bakanna ni ti ẹgbẹ Mabaọlajẹ t i Ọba Adele. Diẹ ninu awọn dẹ ti ra awọn iwe wọnyi. Wọn wa kọ oruko awọn ti o ti ra awọn iwe ẹgbẹ wọnyi ninu wọn ranṣẹ si alaṣẹ Ijọba, wọn tilẹ tun kọ awọn nomba awọn iwe wọnyi pẹlu.

Lẹhin igbati awọn o ti ni isọ tẹlẹ ko ti ri isọ gba tan ninu isọ Ereko titun ti wọn kọ, awọn ọmọ diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Igbimọ Eko ti fi eru gba iwe aṣẹ isọ tan fun awọn aya, alabagbe, ale, aburo ati ẹgbọn wọn lobirin wọn wa tun ṣe iyagan nipa fifi orukọ awọn aya tabi ale, pẹlu aburo tabi ẹgbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Igbimọ ti a ti fi eru gba isọ fun wọnyi ranṣẹ pẹlu.

Wọn wa pari iwe wọn pẹlu awọn ọrọ wọnyi. "Iwakuwa pẹlu ohun aitọ ti Igbimọ Eko wa ṣe ni wipe isọ titun ti wọn kọ ko tobi to ti tẹlẹ ri, a t i p e ṣile marun ni awọn ti nsan fun isọ ti lailai ti o tobi ri, ṣugbọn nisisinyi ṣile mẹwa mẹwa ni wọn ni ki awọn wa san fun isọ kekere titun ti wọn kọ, atipe tẹlẹtẹlẹ enia mẹrin lo ti nwa ni isọ ti o tobi, ṣugbọn eyi ti o kere yi ni wọn wa ni ki enia mẹfa wa lo. "Eyi wa jẹ ohun i n i r a fun wa." Wọn wa bẹ Alaṣẹ Ijọba pe ki o ri pe otitọ leke ninu ọrọ ti o wa nilẹ nisinyi, ki rogbodiyan miran ba ma tun ṣẹlẹ.

## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alọta to dara ju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹ ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ Igbado ati Ọka-Baba, ati Ẹwa-ere origirisi.

**£45 ni a nta** Pelu Ẹnjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Elẹtiriki Mọtọ.

O WA NI ṢỌBU

**Akoshile Brothers**

35, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

### OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣẹpe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu. Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi jẹdi Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde. osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti koṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, tete lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d
LILO RẸ:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West
Lagos Nigeria.
Phone 22515

34, Docemo Street
Lagos
Phone 204247

BARIKA DE SALLAH

# Bismilai Rahmoni Rahim
## NIPA ISLAM

Lati Ọwọ:— ALUFA HUSAEN MUHAMMAD.
No. 10A. Thomas Street. Lagos.

## "Odun Itunu Awe"

INU MI DUN lati ki gbogbo enia ku ọdun ati iyedun Ọlọrun koṣe ọdun ni abo, Amin. Lẹhin ti ati fi ebi dan ara wa wo fun odin-di ọgbọn ọjọ lati le mọ gẹgẹbi otiṣe nri ni ara ati ki aleni anu loju fun awọn alai korijẹ ati alaiko ri mu, owa yẹ ki a mọ ohun ti a gba Awẹ le lori gan gidi.?

Eyi na si ni wipe ki a ma tọrọ anu tabi kia ma ṣe sara. Orişi sara mẹta ni ofin fi kọwa lati ṣe ninu akoko Ọdun yi. Emi yio si fẹ ki ẹgbọ alaye mẹteta na gẹgẹbi Kurani tiṣe wi, ki ẹ si mu ṣẹ ki Ọlọrun Ọba ọga ogo gba ni ẹsin fun wa kio si yọnu si wa (Amin.)

Orişi sara Kini ni ọran yan saka yiyọ lori Dukia rẹ tabi nkan oko tabi owo, ki asi fi fun ọkan ninu awọn enia mẹjẹjọ ti Ọlọrun. Wo inu Kurani, ori; 9, ẹsẹ 60. bayi:- Awọn Talika, awọn Atọrọjẹ, awọn Alufa Oluṣe iṣẹ ẹsin awọn ti o wa ninu igbekun ẹru awọn ti o wa lori ogun ẹsin ati ni oju ọna idagba soke ẹsin, ati onirin ajo ti owo da fun.

Orişi sara Kẹjiti atun ni lati ṣe ni ẹhin Awẹ, ani ni owurọ ọjọ Itunu gan ni "Jaka" Onjẹ ti o ba wọpọ-ju ni Ilu enia ni a fi nṣe eyi. Odi-wọn rẹ si ni ẹkun ọwọ mejeji ni ẹmẹrin fun ẹnikọkan. Bale ile logbọdọ ṣe eyi fun ara rẹ, Aya rẹ, ọmọ rẹ, ati gbogbo awọn enia mẹjẹjọ ti ati ka lẹkan yẹn, ṣiwaju ki a to jade lọ si ọdun, ni owurọ.

Orişi sara kan to ku ni lori irin ijade lọ si ọdun eyiti ani lati maṣe fun idupẹ fun Ọlọrun lori alafia biba awẹ ọgbọn ọjọ de ilẹ, fun atewọ gba ọrẹ ni oju ọna ọdun.

Fun alafia ara wa ni Ọlọrun ṣe mu awọn ofin wọn yi wa. Ki ẹni ti ko ri jẹ ba le fun ẹni ti orijẹ· Kio ma si si kun mu ni ibikan si ẹnikan, Ki gbogbo wa le jẹ ki asi mu laiko ni lọ ba alafia ti ẹni-keji jẹ.

Ki Oluwa fun wa ni ọpọ arisiki ati ẹmi gigun ki a le ma fi pa ofin rẹ mọ, ki o si ṣe ọdun ni Abo o.

Moki gbogbo awọn Onkawe Irohin Imọlẹ pe "BARIKA DE SALA!!

Fi Ibere rẹ ranṣẹ si:- -
Alufa Husaen Muhammad
10A, Thomas Street, Lagos
Ngo si da yin lohun.
Odigboṣe.!

## Itumo Ala awon Onibere

AKINWALE FESITAN

Ṣọra gidigidi lasiko yi ki wọn ma ba gbe ọ da awọn ẹniti o sun mọ ọ ni yio ṣe ọ ni jamba yi, maṣe finu han ẹnikẹni.

Bere ala rẹ lọwọ Joseph Alala 6 Ojo road Mushin

## Itumo Ami ara.

Ẹniti o ba ni ami dudu ni gigirisẹ, yio jẹ alarinkiri ni ọjọ aiye iṣẹ aṣelagun ni yio ma ṣe, ere kiun ni yio si ma ri, ni kukuru ati ni owo rẹ di aiye atunwa. Iwọ ha ni ami lara bi?

Bere itumọ ami ara rẹ lọwọ
Onimimọ Ijinlẹ
6, Ojo Road,
Oduabọrẹ Mushin

## Imoran nipa Ife

BỌSẸDE/ Akokoro ti ka ehin iyawo mi tan, oju wa nti ini lati ma ba rin loju titi kini ki nṣe Bọsẹde?
Emi ni Ajiṣafẹ Eko.

## Itumo

Ajiṣafẹ Eko/ Mo gba ọ ni iyanju pe ki o lọ ra ehin fun ni ọdọ awọn Dokita ẹnu rẹ ti o dahoro yẹn yio wa dabi ti ọmọde.

Bere imọran tirẹ papa lọwọ Bọsẹde 6, Ojo Road Oduabọrẹ Mushin.

BARIKA DE SALLAH E KU ODUN ASE EYI SE AMODUN


# ṣile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Şile kan pere ni owo rira rẹ, koro ẹgbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kọlu o tabi ẹbi rẹ. Mura silẹ.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni şile kan loni!

## 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO

# MA FI OWURO S'ERE APA 9

Lati Qwo: J. O. SHOYINKA (Mushin)

## AKỌ OKUTA KO WỌN JADE PẸLU AYAJỌ

Gẹgẹbi mo ti sọ ni osẹ to koja pe, nigbati wọn sa Omiran ni iṣakuṣa tan o, o wa ku ọna ti a o gba jade ninu ọgbun ainireti yi, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mọ ọwọ yipada ninu nyin ki o yara tete bẹrẹsi pitu inu rẹ, nitoripe ni wakati diẹ si, a ko mọ ohun ti o le ṣẹlẹ si wa nihin. Ko ni lati jẹ wipe Omiran ati Onibode ti a pa nikan ni ikawọ ọgbun yi wa lọwọ rẹ, o nilati jẹ wipe awọn ẹbi nwọn re ajo ni, wọn ko si ni pẹ dẹhinbọ. Ti wọn ba si de, ti wọn si ri pe ati pa awon Olori wọn, ẹ ro wo, ti ẹnyin ba wa ni iru ipo yi kini ẹ o ṣe? ki nma purọ tan yin jẹ, ọpọ-ọrọ ni eṣu fi nyọ, ti wọn ba pọ ju wa lọ, finrinfinrin ni wọn yio pawa, ti a ba ku jẹjẹ nba san, mo mọ dajudaju pe iku oro ni wọn yio fi pa wa.

Ni kukuru Akọokuta rẹrin musẹn, o ni ẹda ko mọwọ yi pada. Ọlọrun ni o ṣeṣẹ, inu bi Mafarọ-ṣẹre, o ni jọwọ ọrẹ mi sọrọ si ọkankan ọna, ẹda ọrọ ko ṣiṣẹ lasiko ti a wa yi, ti o ba mọ nipa rẹ ni ki o wi, ki a le mọ iru ipo ti a wa.

## AKỌ OKUTA TUN RẸRIN MUSẸN

Akọ okuta tun rẹrin musẹn, o ni ologun ridi launlaun ni emi iṣe takute lo mu aparo ni o ba di ẹgbẹ ẹiyẹkẹyẹ nigbati mo wa ni ilu nai, mo le sọ oke di ilẹ, bi mo ti ni ogun rere lọwọ bẹna na si ni ogun buburu nbẹ lọwọ mi nko jẹ akọ okuta lasan, awọn ara ilu mi ni wọn sọ mi bẹẹ, nitoripe ti mo ba di gbolu enia o gbe, ti enia ba si di gbolu mi o kẹran, bi Oluwa ko ba si kọṣe ẹru rẹ n go gbe nyin jade lailewu ninu ọgbun buburu yi awọn ẹlẹgbẹ rẹ duro, wọn nwoye.

Akọ okuta ni ki gbogbo wọn di oju, wọn si diju, o wa bẹrẹsi pe ayajọ kikankikan. O ni ki nwọn laju, Ilaju ti wọn laju ode keji ọgbun ni gbalasa Ọdan ni wọn ba ara wọn, olukuluku bẹrẹsi wa wo kookoo. Mafarọṣẹre dupẹ lọwọ rẹ o ni buruburu ki o ma ku ẹnikan mọ ni o, o ṣeun o, ṣugbọn iṣẹ tun nbẹ niwaju wa, bi enipe ko mai ti sọ ọrọ rẹ tan ni, atẹgun lile bẹrẹsi fẹ, ko pẹ lẹhinna ni Ija bẹrẹsi yi bọ raninranin, ọrọ wa di bo lọ yago lọna fun mi, se ẹnyin papa mọ pe ẹniti ija ba kọlu yio sọ di ero ni. wọn fẹṣẹ fẹẹ bi wọn ba ni ki wọn salọ si apa gusu wọn a pa de Ija. Wọn sa gba apa ariwa Iwọ Orun ati ila orun nṣe ni Ija yi wọn ka, to si nja ranin ranin bọ wa si ọdọ wọn. Iwaju ko ṣe lọ bẹni si ni ẹhin ko ṣe pada si, wọn wa duro bi Sigidi, wọn nwo koran.

Iye inu wọn ti parẹ, akọokuta papa ti wọn gbẹkẹ'e ti dọọdin. Nigbati o ku sata ki Ija de ọdọ wọn o parẹ atẹgun si tọlẹ wọ. Ṣiṣiju ti nwọn yio ṣiju soke, awọn Irunmalẹ li wọn ri lọ rẹpẹ'ẹ. Iriri ati wiwo wọn dẹruba enia, olukuluku wọn si mu ohun ija buburu jọwọ.

Akiyesi:— Lọsẹ to mbọ lagbara Odua ẹ o ma ka apa Kẹwa (10.)

Moki gbogbo o'luka Iwe Irohin Imọlẹ E ku ipalẹmọ ọdun o, Oluwa Alanu yio se ọdun na ni ọdun rere fun gbogbo wa. Amin Aṣẹ.

## Ẹgbe Akorin Titun

Awọn Ẹgbẹ Akọrin I'Ile-Ọlọrun ti awọn ọmọ lẹhin Jesu ti da ẹgbẹ kan silẹ ti oruko rẹ nje Associati on of Church Musician, Eni Ọwọ Dokita J. A. Lucas ni wọn si fi ṣe Baba ẹgbẹ wọn.

Idi rẹ ti wọn fi ṣe da ẹgbẹ yi silẹ ni ni lati ma kojọ, tumọ ati wiwa ri awọn Orin ati ohun ilẹ wa, ti yio jẹ lilo ni ile Isin Ọlọrun.

Awọn ẹgbẹ titun yi wa bẹbẹ fun nkan wọnyi:-

1. Orin titun ti yio ṣe lo ni eto ajọyọ Ominira.
2. Orin titun fun lilo ni ile ẹsin. Gbogbo orin titun yi ti ẹ ba kọ ni ki ẹ fi sọwọ si Igbimọ, lati ọwọ Akọwe ẹgbẹ, ki o to di ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu May 1960.

